STRONG TOWER ACADEMY

KILAASI : SS2

ISORI ISE: IGBAGBO YORUBA NIPA OLODUMARE

OSE KEFA

PERIOD(1&2)

## IGBAGBO YORUBA NIPA OLODUMARE

Awon Yoruba gbagbo wi pe Olorun ni o te aye do. Oun ni o da aye ati awon eda inu re. Oun ni awon Yoruba n pe ni Olodumare, Eledaa, Adakedajo, Alewilese, Atererekaye /Atererekariaye, Alalafunfun, Arinurode, Olu-orun, Olumoran-okan, Oba-orun.

Oruko wonyi n fi owo, ola, iyi ati ise Olorun han. Bi apeere:

### ITUMO AWON ORUKO OLORUN

i. Eledaa / adedaa/ aseda: Eni ti o ni eda, ti o da eda, ti o se eda. O da ohun gbogbo bii eranko, eye, eeyan ati bee bee lo.
ii. Olorun: Olu orun, eni ti o ni orun/ eni ti o tobi ju ni orun
iii. Olodumare: Won fi titobi ati agbara re we odu, iyen ohun to tobi ju lo.
iv. Atererekaye: Eni ti agbara, titobi ati ola re ka gbogbo aye.
v. A-beti-lu-kara-bi-ajere: Eni ti o ni eti ni gbogbo ara, ti o n gbo gbogbo ohun ti eda n so.
vi. Awamaridii: Eni ti a ko le ridii ise re.
vii. Oyigiyigi: Eni ti titobi re ko se e fi we.

viii. Olumoran-okan: Eni ti o mohun ti a n ro lokan.
ix. Adakedajo: Eni ti o n se idajo ninu idakejeje re.

PERIOD(3)

i. Igbagbo awon Yoruba nipa Olodumare jeyo ninu asa ati ise won. Bi apeere:
Awon Yoruba gbagbo pe ko pe meji: Wo si fi titobi agbara Re we ti erin ninu igbo. Won pe e ni “Okan soso ajanaku ti i migbo kijiki”.

ii. Won gbagbo pe kii ku, kii sa. Won pe e ni “ Oba aiku, oba aisa”.
iii. Won gbagbo pe alaaanu ati onidajo ododo ni Olorun.Won a ni ki eeyan “Fija fOlorun ja fowo leran”.
iv. Won pe e ni : A-ko-ma-tika-leyin. A-duro-gboingboin-leyin-asooto”.
v. Nitori wi pe ko si ibi ti oju Olorun ko to, won a maa pede wi pe “Amookun jale, b’oba aye o ri o, torun n wo e” tabi “A-tafa-soke-yido-bori, b’oba aye o ri o, torun n wo e”.
vi. Awon Yoruba gbagbo pe awon ni lati maa fi oruko Olorun saaju ninu ohunkohun ti won ba n se. Won gbagbo pe bi ko ba si Olorun, ko sohun ti eeyan le se.
vii. Awon Yoruba gbagbo ninu awon oruko ti Olorun n je. Bi apeere: Atobajaye, Afunnimasiregun, Awimayehun, Alewilese, Atobiju, Olowogbogboro-ti-yomo-re-lofin ati bee bee lo, won si maa n lo won ninu adura.

viii. Laaarin awon Yoruba, won gbagbo pe Olodumare ni Olorun oun si ni o da awon orisa. Awon orisa je onigbowo laaarin Olodumare ati awon eeyan.